# Alaye bi Anabi sen kirun «s.a.w» 1

Sunna ni fun Imam ati adarun ki kiwọn fi gaga si waju, gaga ti Imam si jẹ gaga fun awọn ti o wa lẹyin rẹ.

Yio da oju rẹkọ ibi ti ofe fi oribalẹ si, kosi gbọdọ yiju kuro.



1

Yio jẹki alafo ti o wa laarin ẹsẹ rẹ dabi iyi ti o wa laarin awọn ejika rẹ, ki o ma lekun tabi dinku, ki o sise ita wọn deede.



2

Lẹyin ti o ba ti pe awọn majẹmu Irun, yio sọpe "Allahu Akbar" pẹlu gbigbe ọwọ mejeji soke lọ sibi eti tabi ejika ti awọn ọmọ nika yio lẹmọ raawon, yio jẹki atẹlẹ ọwọ rẹ dojukọ qiblah.



3

Lẹ́yìn náà, yio gbé inú àtẹ́lẹwọ́ ọ̀tún rẹ̀ sí eyin àtẹ́lẹwọ́ òsì rẹ̀ àti ọrun ọwọ ati apá, "sí àyà rẹ̀" tàbí kio gbámú.



4

Lẹyin naa afẹ ki o ka adua ibẹrẹ ni rakah alakọkọ nikan, Iyi ti o si daaju nipe ki o ka orisi risi awọn adura ibẹrẹ.
Kio sọ bayi wipe : Subhaanaka Allahuma wabihamdik, watabarak asmuka, wata'ala jadduk, wala ilaha gairuk.

Lẹyin naa yio wa aabo pẹlu adura, gẹgẹ bi kosọ wi pe: "A'uzdu billahi mina shaitani rajim".

Lẹyin naa yio se bismillahi, yio si ka faatia daada, ti awọn aaya rẹ, yio tẹle rawọn.
Bismillahi Rahmani Rahim (1) Al-hamdulillahi Rabil a'lamin (2) Arahmani Rahim (3) Maliki yaumiddin (4) Iyyaaka na'budu wa iyyaaka nasta'in (5) Ihdina ssiraatal mustaqim (6) Siraata ladhina an'amta 'alaihim ghairil maghdubi 'alaihim wala ddaalin (7).

Lẹyin naa yio ka ohun ti o rọrun fun lati inu Al-Qur'aani lai se Awuusu billahi, Yio maase bisimillahi ni ibere awon Surah nikan.

5

Lẹyin naa yio gbe ọwọ rẹ soke bi o ti gbe soke nibi takbeera alakọkọ ni ẹni ti o sọpe "Allahu Akbar" ti o si rukuu, lẹyin naa yio di awọn orunkun rẹ̀ mu, kosi gbọdọ tẹ igunpa rẹ̀, o si gbọdọ jẹki ẹyin rẹ ṣe deede ori rẹ, yio si sọ bayi wipe: "Sub'haana Rabiyal Azim" Osi le fi adura towa ninu sunna kún pẹlu.



6

Lẹ́yìn náà, ti oba tin gbe ori lọ soke, kí ó tó nanro, yio sọ pé: " Samia' Allahu liman hamadah" pẹlu pe yio gbé ọwọ́ sókè lọ sibi ẹgbẹ etí tàbí èjìká.

Ti o bati duro deedee, yio sọpe: "Rabbana walakal hamd " Osi le fi adura towa ninu sunna kún pẹlu.

Lẹ́yìn náà, yio sọ takbeera lai gbe ọwọ soke, yio si sujuud lori awọn ẹya ara meje: iwaju ori, imu, atẹlẹ ọwọ mejeeji, orunkun mejeeji, ati awọn ika ẹsẹ mejeeji.

Yio jẹki abiya rẹ jina si ikun ati itan, ba kanaa laarin itan ati ẹsẹ, yio si gbe apá rẹ soke kuro nilẹ.



7

Yio sọ pe: "Subhaana Rabiyal a'laa" lẹẹkan so, Osi le se afikun pẹlu adura tio bafẹ, sugbọn adura sunna lo daa ju.



8

Lẹyin naa yio sọ Allahu akbar, yio si joko si ori ẹsẹ osi rẹ ti o tẹ pẹlẹsẹ silẹ, yio si gbe ẹsẹ ọtun duro, yio si gbe ika ẹsẹ ọtun si ilẹ yio kọsi kibila, yio si gbe atẹlẹ ọwọ si ori itan rẹ yio wa sọ wipe "Robbi igfirli" Ijoko yi ni yio joko ni gbogbo ijoko irun, ayafi nibi awọn irun olopo mẹta ati olopo mẹrin nibi ataaya igbẹyin, yio joko tawaruk nibẹ, ohun nipe yio fi ẹsẹ osi rẹ si abẹ ẹsẹ ọtún.



9

Lẹhinna yio se Allahu akbar, yio si foribalẹ gẹgẹ bi iforibalẹ alakọkọ, lẹyin naa ki o se Allahu akbar, ki o si dide fun rakah ẹlẹẹkeji, ki o se nibe gẹgẹ bi o ti se nibi rakah alakọkọ, ayafi pe kosi kabara ihram ati adura ibẹrẹ nibẹ.



Ti o ba ti pari iforibalẹ ẹlẹẹkeji, ki o joko fun Ataaya.

Yio tọka si waju pẹlu ika ilabẹ, yio siyi ika aarin ati atampako rogodo, yio maa fii soke silẹ, yio maa fi se adura.



Yio si ka Ataaya, lẹyin naa yio se salaatu ibrahimiya: Attahiyaatu lillah, wa salawaatu wa tayyibaat, Assalam alaika ayyuha Nabiyyu warahmatullah wabarakaatuhu, assalam 'alaina wa'alaa 'ibaadillah assaaliheen, Ash'hadu an laa ilaha illa Allah, wa ash'hadu anna Muhammadan 'abduhu warasuluhu, Allahuma sali 'alaa muhammad wa 'alaa aali muhammad, kama salaita 'alaa ibrahim wa 'alaa aali ibrahim; innaka hameedun majeed, Allahuma baarik 'alaa muhammad wa 'alaa al muhammad kama baarakta 'alaa ibrahim wa 'alaa aali ibrahim innaka hameedun majeed.

Lẹhinna yio waṣọ nibi awọn nkan mẹrin yio sọpe: " Allahuma inni a'uzubika min azaabi jahanam, wa a'uzubika min azaabil qabir, wa a'uzubika min fitnati ddajal, wa a'uzu bika min fitnatil mahyaa wal mamat." yio ṣe adura eyi tio bafẹ, ṣugbon adura sunna lo daa julọ, yio ma sope : Allahama a'inni 'ala zikrika wa shukrika wa husni 'ibaadatik

Lẹhinna yio se salama meji si ọtun ati osi rẹ, yio sọ́pe "Assalaamu 'alaikum warahmatullah" yio si yi ori rẹ nikan laiyi ejika, ati lai gbe ori si oke tabi isalẹ, ati lai tọka pẹlu ọwọ mejeeji.



10

ẹniti opese akọsilẹ yi ni : Dọkita Haitham Sarhan, Olukọ ni Mọsalaṣi Anabi ati Alamojuto "Mahadu Sunnah":
MAHADUSUNNAH.COM

Aṣẹ lori titẹẹ ati pinpin oṣikale - Lati tumọ iwe pẹlẹbẹ yi: sarhaan.com tabi yiya koodu yi.